# Dajudaju ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- maa n gbe ọwọ rẹ mejeeji si deedee ejika rẹ mejeeji ti o ba ti bẹ̀rẹ̀ irun,

Lati ọdọ Ọmọ Umar- ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji-: Dajudaju ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- maa n gbe ọwọ rẹ mejeeji si deedee ejika rẹ mejeeji ti o ba ti bẹ̀rẹ̀ irun, ati ti o ba ti kabara fun rukuu, ati ti o ba gbe ori rẹ dide lati rukuu, o maa gbe mejeeji bákannáà, o si maa sọ pé: "Sami'alloohu liman hamidaHu, Robbanaa wa laKal hamdu", ko ki n ṣe bẹẹ nibi iforikanlẹ.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- maa n gbe ọwọ rẹ mejeeji soke nibi aaye mẹta ninu irun ni iwájú ejika ti o ṣe pe: Oun ni ibi ti egungun ejika ati apa ti papọ. Aaye akọkọ: Ti o ba ti bẹ̀rẹ̀ irun nibi kikabara iwọ irun. Ikeji: Ti o ba ti kabara fun rukuu. Ikẹta: Ti o ba ti gbe ori rẹ sókè lati rukuu, ti o wa sọ pe: Sami'alloohu liman hamidaHu Robbanaa wa laKal hamdu. Ko ki n gbe ọwọ rẹ mejeeji sókè nibi ìbẹ̀rẹ̀ fifi ori kanlẹ, tabi nibi gbigbe ori sókè lati ibẹ.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3095

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee